UK Health Security Agency

NHS

# **Lílo paracetamol láti dènà àti tọ́jú ibà àti lẹ́yìn abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB**

### Ọmọ mi ṣẹ̀ṣẹ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB, kinni ki nma reti nibayi?

O le maa reti iba lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára, sugbọn o wọpọ nigbati o ba gba abẹ́rẹ́ MenB (Bexsero) pẹ̀lú eto àjẹsára miiran ni osu 8 ati 12. Laisi paracetamol, ju ilaji awọn ọmọ lo ma ni ara gbigbona lẹyin awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára.
O seeṣe ki iba naa wà ní góngó ni bii wakati 6 lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára o si le lọ patapata laarin ọjọ 2.
Iba naa s'afihan pé abẹ́rẹ́ àjẹsára naa ba eto àjẹsára ọmọ naa mu, biotilẹjẹpe ipele iba niiṣe pẹ̀lú ọmọ kọọkan kosi s'afihan bi abẹ́rẹ́ àjẹsára naa yoo ṣe dabobo ọmọ naa si.

### Báwo ni mo ṣe le dín ewu ibà náà kù?

Gbigba paracetanol kete lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára - lai duro de ki iba kankan waye - yoo din ewu ki ọmọ rẹ ni iba. pẹ̀lú paracetamol, o din diẹ si ọmọ kan ninu marun yoo ni iba ati wipe gbogbo iba wọnyi ko le (o keere si 39°C). Paracetamol yoo dín ààyè kí ọmọ naa ni irira tabi inira kù (bii ara riro ni oju abẹ́rẹ́).

### Èwo nínú irú paracetamol ni kí nlò?

O gbọdọ lo **paracetamol ọmọde olomi. Irú paracetamọl yìí má ńwà ní olómi fún ìlò àwọn ọmọ ọwọ́ àti ọmọdé. Ó ní agbára 12mg/5ml.**

Bi o ko ba tii ni paracetamol olomi n'ile fun awọn ọmọ wẹwẹ, o gbọdọ ra awọn kan ni ile ita oogun agbegbe rẹ tabi ile itaja igbalode ki o le fun-un ni oogun paracetamol akọkọ laarin wakati kan gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára. Orisirisi iru paracetamol lati yan (pẹ̀lú igo ati ọra) sugbọn iru eyiti o nilo paracetamol olomi awọn ọmọde 120mg/5ml.

(Note: Paracetamol ọmọ kekere (ọdun 6 soke) le ju paracetamol ọmọ ọwọ (250mg/5ml) kosi gbọdọ jẹ lilo fun awọn ọmọ ọwọ.

### Lẹyin iru abẹ́rẹ́ àjẹsára wo ni mo gbọdọ gba paracetamol fun ọmọ mi?

A damọran paracetamol fun ọmọ-ọwọ rẹ ni titẹle awọn eto gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB ni à má ńsábà gún ní àwọn ìpàdé gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára àkọ́kọ́ àti ikẹta ọmọ rẹ ní ọjọ́-orí osù 8 àti osù 12.

Paracetamol ko saba nilo lẹyin gbigba alekun abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB ni ọjọ-ori osu mejila.
Ní ọjọ́-orí yìí, ewu ọmọ náà si ibà jẹ bakanna bi awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára yooku.

### Iwọn paracetamol wo ni ki n fun-un?

A d'amọran apapọ iwọn oogun paracetamol mẹta ti 2.5ml (60mg) lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. O gbọdọ gba abẹ́rẹ́ akọkọ ni akoko gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára tabi ni kiakia lẹyin igba naa.

O wa gbọdọ fun-un ni oogun paracetamol keji ni nkan bii wakati 4 si 6 lẹyin naa ati oogun kẹta ni wakati 4 si 6 lẹyin naa (wo tabili).

O gbọdọ wọn 2.5ml ki o si fun-un boya pẹ̀lú ike abẹ́rẹ́ tabi pẹ̀lú sibi iwọn 2.5ml (eyi ni sibi kekere to saba ma nwa pẹ̀lú pali).

Fun awọn ọmọ ti ko gbo (ti wọn bi saaju ọsẹ ibimọ 32), dokita rẹ gbọdọ pelo paracetamol ni ibamu pẹ̀lú iwọn ọmọ naa ni akoko gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára. O gbọdọ ṣe ayẹwo pẹ̀lú dokita rẹ ki o si tẹle awọn ifilọ to wa lori ọna lilo oogun.

### Iwọn ilo àti àkókò paracetamol olomi fun ọmọ ọwọ (120mg/5ml) fun ilo lẹyin awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB akọkọ gba (ó sábà jẹ osù 8 ati osù 12 l'ọjọ ori)

| Ọjọ-ori ọmọ | Tití dé osù 6 (ó sábà jẹ osù 8 àti osù 12) |
|---|---|
| Oogun lilo 1 | Oogun 2.5ml (60mg) kan ni kete lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ aj]esara. |
| Oogun lilo 2 | Oogun 2.5ml (60mg) kan ni wakati 4 si 6 lẹyin oogun akọkọ |
| Oogun lilo 3 | Oogun 2.5ml (60mg) kan ni wakati 4 si 6 lẹyin oogun keji |

immunisation

Ọna ti o laabo julọ lati daabobo ilera ọmọ rẹ

**Imọran inu iwe pelebe yii kàn ọ nikan bi ọmọ rẹ ba gba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Bi ọmọ rẹ ba ni iba ni akoko miiran o gbọdọ tẹlẹ awọn imọran naa ati awọn imọran ara ike oogun ati iwe iwifun alaisan.**

### Bi ọmọ mi ba si ni iba lẹyin lilo awọn opgun paracetamol mẹtẹẹta?

Awọn ọmọ miiran si le ni iba lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára, koda lẹyin lilo awọn oogun paracetamol metẹẹta. Ni wakati 48 lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára, bi ọmọ rẹ ba si ni iba sugbọn ti kosi gbadun, o le tẹsiwaju lati maa fun ọmọ rẹ ni iru iwọn 2.5 ml (60mg) paracetamol olomi (120mg/5ml) ọmọ ọwọ kanna ninu.

- **O gbọdọ maa fi o keere tan wakati 4 silẹ laarin awọn oogun lilo nigbagbogbo ki o si maṣe fun-un ju oogun 4 lọ ninu eyikeyi akoko wakati 24.**

O si tun gbọdọ fi ara rẹ balẹ nipa riri daju wipe wọn koni ipele asọ tabi ibora to pọ, ki o si fun wọn ọpọlọpọ omi. Bi ọmọ rẹ ba nmu ọyan, omi to dara julọ lati fun-un ni omi ọyan.

- **Bi o ba ni ifoya nipa ilera ọmọ rẹ ni akoko kankan, lẹyin-naa gba ero rẹ gbọ ki o si ba GP rẹ sọrọ tabi ki o pe NHS 111 ni orilẹ-ede England ati 0845 46 47 ni Wales fun imọran.**
- **Bi ọmọ rẹ ba si tun ni iba ju wakati 48 lọ lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára o gbọdọ ba GP rẹ sọrọ tabi ki o pe NHS 111 ni orilẹ-ede England ati 0845 46 47 ni Wales fun imọran.**

## Awọn ibeere miiran to wọpọ:

### Njẹ mo le ji ọmọ mi lati fun-un ni paracetamol?

O gbọdọ gbiyanju nigba gbogbo lati fun-un ni ogun paracetamol akọkọ ni kete lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Ẹwẹ, bi ọmọ rẹ ba nsun nigbati akoko oogun lilo keji ti to, maṣe ji wọn O le lo fun-un nigbati ọmọ ba ji bi o ba jẹ pe o keere tan wakati 4 wa laarin lilo oogun kọọkan.

### Njẹ o dara fun awọn ọmọ wẹwẹ lati lo paracetamol?

A ti fọwọsi paracetamol lati s'akoso iba ninu awọn ọmọde lati osu 2 lọjọ ori. Iwe iwifun pelebe to ba pali naa wa le sọ wipe ọmọ osu 2 si 3 ko gbọdọ gba iwọn oogun meji saaju biba dokita tabi akọṣẹmọṣẹ oogun oyinbo.

Biotilẹjẹpe paracetamol ko l'ewu ninu awọn ọmọ wẹwẹ, imọran ara ike/pali wa nibẹ lati dena ki awọn obi fun ọmọ ni paracetamol pẹ̀lú iba ti wọn ko le s'alaye. Iru iba naa le jẹ aami aarun lile to si jẹ wipe siṣe itọju eyi fun igba pipẹ le ma jẹki obi wa iranlọwọ iṣegun mọ.

Gẹgẹbi iba lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára ti wọpọ, ẹwẹ, awọn akọṣẹmọṣẹ ti gbamọran pe o DARA lati lo paracetamol titi yoo fi di wakati 48 lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB lai gba imọran iṣegun.

Iba ni akoko yii le seeṣe ki o waye nipaṣẹ abẹ́rẹ́ àjẹsára ju nipasẹ aranmọ lọ. Paracetamol yoo tun jẹki ọmọ rẹ ṣe daradara, ati wipe kosi ewu oogun aloju bi o ko ba fun-un ju iwọn 2.5ml lọ lẹẹmẹrin laarin wakati 24.

### Kini idi ti iwe iwifun alaisan pelebe ti oloogun (PIL) ṣe ni orisirisi iwifun?

Wa ri iwe iwifun pelebe (PIL) ninu pali paracetamol ti o ba ra. PIL to wa pẹ̀lú paracetamol olomi ọmọ-ọwọ 120mg/5ml le pese orisi ikilọ lilo oogun fun lati ibi awọn aba imọran awọn akọṣẹmọṣẹ fun ilo ni titẹle abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Nibi, ninu iwe pelebe yii, a fun ọ ni awọn alaye awọn pato aba imọran fun ilo paracetamol ni titẹle abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Fun iwifun kikun nipa iru paracetamol, jọwọ wo PIL oluṣeda oogun.

### Njẹ ọmọ mi nilo paracetamol pẹ̀lú awọn alekun abẹ́rẹ́ àjẹsára ni osu 12?

Ni ọjọ-ori osu 12 ewu iba ọmọ rẹ lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB jẹ bakanna pẹ̀lú awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára yooku. Nitorinaa, ọmọ rẹ ko nilo lati lo iwọn oogun paracetamol 3 pẹ̀lú awọn eto gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára olosu mejila. Ẹwẹ, bi ọmọ rẹ ba ni iba ni ile tabi dabi ẹnipe o nfa inira, o le fun ọmọ rẹ ni paracetamol ọmọde nipa lilo eto oogun naa fun ọmọ toti de ọjọ-ori yẹn gẹgẹbi o ṣe wa ninu ifilọ inu paali naa.

**Imọran lati lo ju oogun paracetamol lẹẹmeji fun awọn ọmọ ti wọn ti pe osu 2 si 3 waye nikan lẹyin ti ọmọ naa ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára MenB. Bi ọmọ rẹ ba ni iba ni akoko miiran o gbọdọ tẹlẹ awọn imọran naa ati awọn imọran ara ike oogun ati iwe iwifun alaisan.**

**www.nhs.uk/vaccinations**

© Crown copyright 2025. Version 4. UK Health Security gateway number: 2025-168. Product code: 3083756YOR Yoruba. 50K SEP 2025 (APS)
To order more copies of this asset, please visit: **www.healthpublications.gov.uk** or call 0300 123 1002.